**STA YORÙBÁ**

**J.S.S. 2 Notes**

**ÒSẸ̀ KARÚN-UN 5th Week.**

**KÓKÓ – IṢẸ́ : ÀṢÀ IKÍNI NÍ ILẸ̀ YORÙBÁ.**

Oriṣìíriṣìí ni àwọn Yorùbá n ki ara wọn ní ilẹ̀ Yoruba. Wọn ní ìkíni àsìkò\Àkókò, Ìkíni bí ìgbà ṣe ń yí padà, Ìkíni lẹ́nu iṣẹ́ abbl.

Lára àwọn ìkíni ilẹ̀ Yorùbá.

| | |
|---|---|
| 1. Ẹni tó ṣẹ̀ṣẹ̀ bímọ | Ẹ kú ọwọ́ lómi o |
| 2. Ìsìnkú Àgbà | Ẹ̀yìn Òkú á dára |
| 3. Ìgbéyàwó | Ẹ̀yìn Ìyàwó kòní mọ ẹní |
| 4. Ọdẹ | Àrìnpa Ògún o |
| 5. Aláboyún | Àfọ̀n á gbó kó tó wọ̀ |
| 6. Awakọ̀ | Àwàyè ọkọ̀. |
| 7. Àgbẹ̀ | Àroko bọ́dún de o |
| 8. Alágbẹ̀dẹ | Àrọyè. |

Gbogbo iṣẹ̀lẹ ni àwọn Yorùba ní ìkíni fún

**ÌGBÀ KEJI. (Second Period)**

**J.S.S. 2. Note.**

**KÓKÓ – IṢẸ: ÌṢẸ̀DÁ Ọ̀RỌ̀ ORÚKỌ:**

Ìṣẹ̀da-ọrọ: Ni ìlàna ti a ń tẹ̀lé láti sẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun. Àwọn ìlànà láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun ni:

(i) Lílo Mọ́fiimù àfomọ́ ìbẹ̀rè pẹ̀lú mọfiimú àdádúró : B.A A + dé = Adé

Í + fẹ́ = ìfẹ́ , ai + sùn = àisùn , ai + san = aisan

(ii) Lílo àfomọ́ ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú Mọ́fíímù àdádúró tí o jẹ́ ẹ̀rẹ̀ – orúkẹ. B. A "Oní".

Oní + iṣu = oníṣu , Oni + ilé = Onile.

(iii) Fífi àfòmọ́ ààrín bọ àpètunpe ọ̀rọ̀ – orúkọ. B . A

Ọmọ + ki + ọmọ = ọmọkọ́mọ, Ilé + ki + Ilé = ilékílé

ọwọ́ + de + ọwọ́ = ọwọ́dọ́wọ́

.

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ: ASSiGNMENT J.S.S 2.**

**1. Dárú**kọ àwọn ọ̀rọ̀ Àfòmọ́ Ìbẹ̀rẹ̀?

**2. Báwo ni a ṣe ń kí àwọn ènìyàn wọ̀nyi?**

**i. Akọpẹ**

**ii. Ẹni to ṣẹ̀ṣẹ̀ bímọ?**

**Iii Ẹni to n lọ sí ìrin àjò.**

**iv. Onidiri**

**v. Alagbẹ̀dẹ.**